# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kẹ́jọ, Ọdún 2026**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́ OṢÙ KẸ́JỌ, ỌDÚN 2026**

**À NKỌRIN AGBÁR' ỌLỌ́RUN**

1. À nkọrin agbára' Ọlọ́run,
Tó nṣí òkè ní'dì,
Tó nmú àwọn odò nlá ṣàn,
Tó gb'áwọsánmọ̀ ró,
À nkọrin ọgbọ́n Ọlọ́run,
T'òrùn tó nràn lọ́sàn,
Oṣùpá mọ́lẹ̀ l'áṣẹ Rẹ̀,
Ìràwọ̀ bákan nà.

2. À nkọrin ṣe nlá Olúwa,
Tó m'ónjẹ kún ayé,
Ó dá'oun gbogbo pẹ̀l'ọ́rọ̀ Rẹ̀,
Ó wípé wọn dára,
Ìyanu Rẹ ti tóbi tó,
Gbogbo ojú sì nri,
Ní orí ilẹ̀ tí a nrìn,
Àti l'áwọsánmọ̀.

3. Àwọn 'odòdó àt'ewéko,
N'fògo Ọlọ́run hàn,
Ìkúkù àt'ìjì líle,
Wọ́n nsọ t'agbára Rẹ̀,
Gbogbo iṣẹ̀dá ọwọ́ Rẹ,
Ṣì nrí ìtọ́jú Rẹ,
Ibikíbi t'ówù kawà,
Ọlọ́run npẹ̀lú wa.

## ẸJẸ̀ JÉSÙ LÍ AGBÁRA PÚPỌ̀ L’Ọ́JỌ́ WỌNNÌ

**1. Ẹ̀jẹ̀ Jésù lí agbára púpọ̀ l’ọ́jọ́ wọnnì,**
Láti fún olè ní ìgbàlà,
L’ẹ́sẹ̀ kannà ẹ̀mí rẹ̀ fò lọ sí Párádísè,
Níp’agbára ẹ̀jẹ̀ Kálfárì.

Ẹ̀jẹ̀ nà tí nsàn ní Kálfárì,
Agbára rẹ̀ kò yẹ̀,
Ẹ̀jẹ̀ nà kò lè s’agbára rẹ nù,
Kò lè sọnù títí láí.

2. Mo sọnù nínú ẹ̀ṣẹ̀, Ó ta ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ sílẹ̀,
Ó wẹ̀ mí, Ó sọ mí d’omìnira,
Títí di ọjọ́ òní lí ẹ̀jẹ̀ nà nwẹ̀ mí mọ́,
Ògo! Ògo ni fún Olúwa.

3. Arákùnrin mi, èse t’íwọ ó kù n’ínú ẹ̀ṣẹ̀,
Ó tí ṣe ‘pèsè ìgbàlà rẹ,
Wo Jésù, ìwọ yó yè, gba ìyè aìnípẹ̀kun,
Torí Ẹ̀jẹ̀ Kálfárì sì mbẹ.

4. Kó ẹrù rẹ wá l’ónì, kọ gbo’ gbẹ̀ṣẹ̀ rẹ sílẹ̀,
Y’Ó gbà ọ́, y’Ó sọ ọ́ di mímọ́,
Sá àsálà f’ẹ́mì rẹ, aó kọ’rúkọ rẹ sílẹ̀,
Nípa ẹ̀j’Ọ̀dágùtàn l’ókè.

## <u>Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA</u>

1. Àwọn ẹ̀rí lórí ẹ̀rí, ẹ ṣàwárí mi nínú ètò tonìí, ní orúkọ Jésù.

2. Olúwa, bí O ṣe borí òkùnkùn lọ́jọ́ kinní, jẹ́ kí agbára Rẹ borí gbogbo òkùnkùn nínú ayé mi lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Gúnugún òkùnkùn tí wọ́n yàn láti jẹ ẹran-ara mi, iná Ọlọ́run Èlíjàh yóò ṣàwárí rẹ lọ́nìí, yóò sì pa ọ́ run, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn ẹ̀rí mi tó mbẹ lọ́wọ́ ìkà, ẹ gba ìtúsílẹ̀, kí ẹ sì wámirí níbí lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, da òróró títóbi sórí mi báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ohùn ikú àìtọ́jọ́, tó nké lòdì sí mi yóò tapadà lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, fimíṣe àpẹẹrẹ agbára Rẹ tó n ṣiṣẹ́ àrà, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**Orin Dáfídì 34:17:** Àwọn olódodo nké, OLÚWA sì gbọ́, Ó sì yọ wọ́n jáde nínú ìṣẹ́ wọn gbogbo.

**Orin Dáfídì 107:6:** Nígbàná ni nwọ́n kígbe pe OLÚWA nínú ìpọ́njú wọn, Ó sì yọ wọ́n kúrò nínú ìṣẹ́ wọn.

**Orin Dáfídì 50:15:** Kí o sì képè Mí ní ọjọ́ ìpọ́njú: Èmi Ó sì gbà ọ́, ìwọ ó sì ma yìn Mí lógo.

**2 Sámúẹ́lì 22:2:** Ó sì wípé, OLÚWA lí àpáta mi; àti odi mi, àti olùgbàlà mi.

**Orin Dáfídì 34:4:** Èmi ṣe àfẹ́ri OLÚWA, Ó sì gbóhùn mi; Ó sì gbà mí kúrò nínú gbogbo ìbẹ̀rù mi.

**Orin Dáfídì 89:13:** Ìwọ ní apá agbára: agbára lí ọwọ́ Rẹ, gíga li ọwọ́ ọ̀tún Rẹ.

**Ìsáíàh 41:10:** Ìwọ má bẹ̀rù; nítorí m'O wà pẹ̀lú rẹ, má fòyà; nítorí Èmi ni Ọlọ́run rẹ: Èmi Ó fùn ọ ní okun; nítòtọ́, Èmi Ó ràn ọ́ lọ́wọ́; nítòtọ́, Èmi Ó fi ọwọ́ ọ̀tún òdodo mi gbé ọ sókè.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

## ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Olúwa, jẹ́ kí ìfarahàn mi rú àwọn ẹ̀rí sókè, ní orúkọ Jésù.
4. Mo mú ìjákulẹ̀ bá gbogbo ajá tó n gbó lòdì sí alàjá mi, ní orúkọ Jésù.
5. Òòlù Ọlọ́run, bàlé àwọn ọ̀tá mi báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára tó sọ̀rọ̀ sínú ògùn láti fi ìpọ́njú ṣọwọ́ sínú ayé mi, tapadà báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ìwọ aṣọ ṣíṣe làálàá láìlérè, bọ́lulẹ̀, jó di éérú, ní orúkọ Jésù.